3. Gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Jésù Krístì kú fún ẹ̀ṣẹ̀ rẹ lórí igi àgbélébùú, Ó sì jíǹde kúrò nínú òkú.
4. Lẹ́yìn náà, tẹ orí rẹ ba, kí o gba àdúrà yìí:

*Ọlọ́run Ọ̀wọ́n: Mo jẹ́wọ́ pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni mí. Ẹ jọ̀wọ́, Ẹ dárí ẹ̀ṣẹ̀ mi jì mí. Mo ṣetán báyìí láti kọ ìgbésí aiyé ẹ̀ṣẹ̀ mi sílẹ̀. Mo gbàgbọ́ pé Ọmọ Yín, Jésù kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi, Ó jíǹde kúrò nínú òkú, Ó sì wà láàyè. Mo jẹ́wọ́ ọ Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà mi, mo sì pè é láti jọba nínú ọkàn mi láti òní lọ. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ, Jésù Krístì, tí O kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi kí n lè rí ìdáríjì gbà, kí n sì lè ní iyè àinípẹ̀kun. Àmín.*

Tí o bá gba àdúrà yìí látọkànwá, a bá ọ yọ̀, nítorí o ti di ọmọ Ọlọ́run báyìí (Jòhánù 1:12-13).

### Kílọ́ kàn lẹ́yìn Ìgbàlà?

Ó ṣe pàtàkì pé kí o máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́ lẹ́yìn tí o bá ti ní ìgbàlà. Wá Bíbélì kan, kí o bẹ̀rẹ̀ sí kàá lójoojúmọ́. Gbogbo ohun tí o ní láti mọ̀ nípa Ọlọ́run, àwọn èro Rẹ̀ sí ọ, àti bí o ṣe lè gbé ìgbésí aiyé tí ó wù ú wà níbẹ̀. Wá ṣọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì kan ní àdúgbò rẹ, kí o lè gba ẹ̀kọ́ tí ó múnádóko láti inú Bíbélì. Lọ sí ibẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, kí o sì gbèrò láti máa lọ déédé. O lè kàn sí wa nípa ìgbésí aiyé tuntun rẹ nínú Krístì, nípasẹ̀ ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa (Divine Literature International tàbí Dove Letter Zone). Má jáfara láti lo àwọn ohun ìtọ́sọ́nà mìíràn níbẹ̀ tí yóò wúlò fún ọ, pẹ̀lú. Káàbọ̀ sí agboolé Ọlọ́run, olùfẹ́!

*Tí ìwé-pélébé yìí bá wúlò fún ọ, jọ̀wọ́ ṣàjọpín rẹ̀ pẹ̀lú ẹlòmíràn.*

**DIVINE LITERATURE INTERNATIONAL**

*~ À ń tan Ìhìnrere Káàrí Aiyé*

**www.divineliterature.org**
**www.doveletters.org**

Divine Literature International ni òǹkọ̀wé ìwé-pélébé yìí. Wọ́n sì mú u wá fún pínpín ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bí Olúwa ṣe ń pèsè. Àwọn Ìwé-pélébé wa kì í ṣe fún títà. Jọ̀wọ́ kàn sí wa nípasẹ̀ àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa tí ẹnikẹ́ni bá ń gbìyànjú láti tà á fún ọ.

©Divine Literature International 2023



## Eré Ìdálẹ̀bi...

Kì í ṣe ohun tuntun mọ́ lóde òní ki àwọn èniyàn máa tọkasi àṣìṣe tàbí àléébù tí ó wà nínú ìwà elòmíràn, gẹ́gẹ́ bí àwáwí láti kọ Ẹ̀bùn Ìgbàlà Ọ̀fẹ́ tí Ọlọ́run fún gbogbo wa. Òmíràn nínú wọn lè ti ní ìpalára tí ó jinlẹ̀ tàbí ìjákulẹ̀. Wọ́n sì ti yàn láti máa bá ìgbésí aiyé wọn lọ láìsí Krístì, nítorí ohun búburú tí Krístẹ́nì àtúnbí tí o jẹ́ alábàáṣiṣẹ́pọ̀, ọ̀rẹ́, aládùúgbò, mọ̀lẹ́bí, tàbí olùṣọ́ kan tí wọ́n gbọ́ nípa rẹ̀ ti ṣe. Tí o bá jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn èniyàn yìí, ó wù wá láti ṣàlàyé àwọn nǹkan méji wọ̀nyí fún ọ:

1. Ó ṣeé ṣe kó jẹ́ pé Krístẹ́nì àtúnbí yìí ò tíì di ẹni pípé nínú Krístì. Jésù Krístì, Ọ̀gá wa ṣì ń ṣiṣẹ́ lórí gbogbo wa títí tí a o fi pé. Ó ṣeé ṣe bákan náà kí èniyàn tí ó ti di àtúnbí kọsẹ̀ nígbà-míràn. Ṣùgbọ́n à ń rí ìdáríjì gbà ní kété tí a bá gbà pé a dẹ́ṣẹ̀ nítòótọ́, tí a jẹ́wọ́ ẹ̀ṣẹ náà fún Ọlọ́run, tí a sì gbé ìgbésẹ̀ tí ó yẹ láti yí padà, nítorí Ọlọ́rọ̀ Àánú ni Bàba wa Ọ̀run jẹ́, àti pé Ọmọ Rẹ̀, Jésù Krístì, Olùgbàlà wa ti san gbèsè

3. Gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Jésù Krístì kú fún ẹ̀ṣẹ̀ rẹ lórí igi àgbélébùú, Ó sì jíǹde kúrò nínú òkú.
4. Lẹ́yìn náà, tẹ orí rẹ ba, kí o gba àdúrà yìí:

*Ọlọ́run Ọ̀wọ́n: Mo jẹ́wọ́ pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni mí. Ẹ jọ̀wọ́, Ẹ dárí ẹ̀ṣẹ̀ mi jì mí. Mo ṣetán báyìí láti kọ ìgbésí aiyé ẹ̀ṣẹ̀ mi sílẹ̀. Mo gbàgbọ́ pé Ọmọ Yín, Jésù kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi, Ó jíǹde kúrò nínú òkú, Ó sì wà láàyè. Mo jẹ́wọ́ ọ Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà mi, mo sì pè é láti jọba nínú ọkàn mi láti òní lọ. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ, Jésù Krístì, tí O kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi kí n lè rí ìdáríjì gbà, kí n sì lè ní iyè àinípẹ̀kun. Àmín.*

Tí o bá gba àdúrà yìí látọkànwá, a bá ọ yọ̀, nítorí o ti di ọmọ Ọlọ́run báyìí (Jòhánù 1:12-13).

### Kílọ́ kàn lẹ́yìn Ìgbàlà?

Ó ṣe pàtàkì pé kí o máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́ lẹ́yìn tí o bá ti ní ìgbàlà. Wá Bíbélì kan, kí o bẹ̀rẹ̀ sí kàá lójoojúmọ́. Gbogbo ohun tí o ní láti mọ̀ nípa Ọlọ́run, àwọn èro Rẹ̀ sí ọ, àti bí o ṣe lè gbé ìgbésí aiyé tí ó wù ú wà níbẹ̀. Wá ṣọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì kan ní àdúgbò rẹ, kí o lè gba ẹ̀kọ́ tí ó múnádóko láti inú Bíbélì. Lọ sí ibẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, kí o sì gbèrò láti máa lọ déédé. O lè kàn sí wa nípa ìgbésí aiyé tuntun rẹ nínú Krístì, nípasẹ̀ ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa (Divine Literature International tàbí Dove Letter Zone). Má jáfara láti lo àwọn ohun ìtọ́sọ́nà mìíràn níbẹ̀ tí yóò wúlò fún ọ, pẹ̀lú. Káàbọ̀ sí agboolé Ọlọ́run, olùfẹ́!

*Tí ìwé-pélébé yìí bá wúlò fún ọ, jọ̀wọ́ ṣàjọpín rẹ̀ pẹ̀lú ẹlòmíràn.*

**DIVINE LITERATURE INTERNATIONAL**

*~ À ń tan Ìhìnrere Káàrí Aiyé*

**www.divineliterature.org**
**www.doveletters.org**

Divine Literature International ni òǹkọ̀wé ìwé-pélébé yìí. Wọ́n sì mú u wá fún pínpín ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bí Olúwa ṣe ń pèsè. Àwọn Ìwé-pélébé wa kì í ṣe fún títà. Jọ̀wọ́ kàn sí wa nípasẹ̀ àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa tí ẹnikẹ́ni bá ń gbìyànjú láti tà á fún ọ.

©Divine Literature International 2023



Eré Ìdálẹ̀bi...

Kì í ṣe ohun tuntun mọ́ lóde òní ki àwọn èniyàn máa tọkasi àṣìṣe tàbí àléébù tí ó wà nínú ìwà elòmíràn, gẹ́gẹ́ bí àwáwí láti kọ Ẹ̀bùn Ìgbàlà Ọ̀fẹ́ tí Ọlọ́run fún gbogbo wa. Òmíràn nínú wọn lè ti ní ìpalára tí ó jinlẹ̀ tàbí ìjákulẹ̀. Wọ́n sì ti yàn láti máa bá ìgbésí aiyé wọn lọ láìsí Krístì, nítorí ohun búburú tí Krístẹ́nì àtúnbí tí o jẹ́ alábàáṣiṣẹ́pọ̀, ọ̀rẹ́, aládùúgbò, mọ̀lẹ́bí, tàbí olùṣọ́ kan tí wọ́n gbọ́ nípa rẹ̀ ti ṣe. Tí o bá jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn èniyàn yìí, ó wù wá láti ṣàlàyé àwọn nǹkan méji wọ̀nyí fún ọ:

1. Ó ṣeé ṣe kó jẹ́ pé Krístẹ́nì àtúnbí yìí ò tíì di ẹni pípé nínú Krístì. Jésù Krístì, Ọ̀gá wa ṣì ń ṣiṣẹ́ lórí gbogbo wa títí tí a o fi pé. Ó ṣeé ṣe bákan náà kí èniyàn tí ó ti di àtúnbí kọsẹ̀ nígbà-míràn. Ṣùgbọ́n à ń rí ìdáríjì gbà ní kété tí a bá gbà pé a dẹ́ṣẹ̀ nítòótọ́, tí a jẹ́wọ́ ẹ̀ṣẹ náà fún Ọlọ́run, tí a sì gbé ìgbésẹ̀ tí ó yẹ láti yí padà, nítorí Ọlọ́rọ̀ Àánú ni Bàba wa Ọ̀run jẹ́, àti pé Ọmọ Rẹ̀, Jésù Krístì, Olùgbàlà wa ti san gbèsè

gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ wa. Nítõtọ́, àwa kìí ṣe àtìlẹ́yìn fún ẹ̀kọ́ *'Rígbàlà Lẹ́ẹ̀kan, O ti Rígbàlà Tití Aiyé'* tí díẹ̀ nínú àwọn olùkọ́ni Krìstẹ́nì ń polongo fún àwọn ènìyàn. Síbẹ̀síbẹ̀, a yóò yára láti jẹ́ kí o mọ̀ pé Krístì kìí kọ ènìyàn tí ó ti gbà á nítòótọ́ gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà rẹ̀, sílẹ̀ (Jòhánù 6:37-39). Bí ó tilẹ̀ jẹ́ bẹ́ẹ̀, ẹni tí ó ti gba Krístì lè pinnu láti yà kúrò lọ́dọ̀ Rẹ̀, kí ó tẹ̀lé ọ̀nà míràn. Nígbà náà ni a óò wá sọ pé ẹni náà ti kúrò nínú Ìgbàgbọ́ nípa yíyàn tirẹ̀. Àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ mìíràn tún ṣì wà - èyí tí a lè parí èrò sí pé ènìyàn ti yà kúrò lọ́dọ̀ Olúwà. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn á máa jiyàn pé, ẹni tí ó yàn láti kúrò nínú Ìgbàgbọ́ kò fi ìgbà kan ní ìgbàlà ní òtítọ́ tẹ̀lẹ̀ rí. Ṣùgbọ́n kókó-ọ̀rọ̀ wa nísìnyí kìí ṣe nípa *Kíkúrò nínú Ìgbàgbọ́* tàbí *Dídúró sínú Ìgbàgbọ́*. Bá wa ká lọ sí àlàyé kejì!

2. Bí Krístẹ́nì àtúnbí (ẹni tí ó ti ní ìgbàlà) kò bá dáwọ́ ẹ̀ṣẹ̀ dúró, Olúwa yóò tọ sí ọ̀nà tí ó tọ́. Kìí ju ẹnikẹ́ni nínú wa nù. Kàkà bẹ́ẹ̀, yóò bá wa wí lọ́ná tí ó wù ú, bí Bàbá tí ó nífẹ̀ẹ́ àwọn ọmọ rẹ̀ ṣe ń ṣe e (Hébérù 12: 5-11).

Gbogbo èyí túmọ̀ sí pé, ènìyàn tí ó ní ìgbàlà yóò ṣe ohun tí ó bá yẹ ní ṣíṣe lọ́dọ̀ Olúwa tí ó bá dẹ́ṣẹ̀, yóò sì rí ìdáríjì gbà, láìsí ìdálẹ́bi. Gbàrà tí ó bá ti ṣe ohun tí ó bá yẹ ní ṣíṣe, Ọlọ́run yóò gbàgbé ẹ̀ṣẹ̀ náà; á sì dàbí ẹni pé kò sí ohun búburú kan tí ó ṣẹlẹ̀ (Àìsáyà 43:25). Kìí ṣe dandan kí ẹni yìí ṣàlàyé ìgbà, tàbí bí ó ṣe ṣe ohun tí ó yẹ lọ́dọ̀ Olúwa fún ọ, láti dá ara rẹ̀ láre lọ́dọ̀ rẹ. Kí ènìyàn jẹ́wọ́ (fún ọ) nípa ohun tí ó ṣe ní tààràtà tàbí láìṣe tààràtà láti pa ọ́ lára jẹ́ ohun tí ó dára púpọ̀; ó sì lè mú àtúnṣe àjọṣe tí o ní pẹ̀lú ẹni náà, wá. Àmọ́, jíjẹ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ fún ẹ̀dá-ènìyàn kìí ṣe ohun àfilélẹ̀ láti rí ìdáríjì Ọlọ́run gbà. Ohun pàtàkì méjì tí a mú ní dan-dan (bí ẹni yìí bá jẹ́ Kristẹni tí ó ní ìdúró rere) ni, kí ó tọrọ àforíjì rẹ, kí ó sì wá ọ̀nà láti ṣe àtúnṣe níbi tí ó bá ti ṣeé ṣe. Lẹ́yìn tí ẹni náà ti ṣe ohun tí ó yẹ, tí ó sì ń bá ìgbésí aiyé rẹ lọ (nítorí àwọn àǹfààní tí ó ní gẹ́gẹ́ bí ènìyàn tí ó ti ronúpìwàdà tí ó sì ti rí ìdáríjì Ọlọ́run gbà), ìwọ ṣì lè máa ba yodì; kí o máa ronú ohun tí ó ṣe sí ọ ní ọ̀sẹ̀ tó kọjá, oṣù tó kọjá, tàbí àwọn ọdún sẹ́yìn, tí kò dára.

Ó ṣeé ṣe ko máa rò báyìí: *"Eléyìí ò dáa"*; àmọ́ Ìgbàlà nípasẹ̀ Jésù Krístì jẹ́ ohun tí ó jẹ́, pàtó: Ẹ̀bùn Àgbàyanu Oore-ọ̀fẹ́ Ọlọ́run tí Ó fi fún ìwọ náà (1 Jòhánù 2:2). Ìwọ yóò fi ayọ̀ du ara rẹ lórí ilẹ̀-aiyé, àti ìdùnnú àìnípẹ̀kun lẹ́yìn aiyé yìí, tí o bá ń kọ Ẹ̀bùn yìí. Gbogbo wa ni a óò gba ìdájọ́ lẹ́yìn ikú (Hébérù 9:27). Ní ọjọ́ ìdájọ́, ìwọ nìkan ni yóò dúró níwájú Olúwà láti gba ìdájọ́ fún ẹ̀ṣẹ̀ rẹ - kì í ṣe ìwọ àti ẹni tí o dá lẹ́bi fún kíkọ̀ láti gba Ẹ̀bùn Ìgbàlà lákòókò tí o wà láiyé. Olúkúlùkù pẹ̀lú Ìgbàlà tirẹ̀! Yóò ti wá pẹ́ jù láti yí ọkàn rẹ padà. Ó ṣeé ṣe pẹ̀lú, kí o rántí pé o ka ìwé àṣàrò kúkúrú yìí *"tí kò ṣe pàtàkì"* sí ọ lásìkò tí o kàá. Gbogbo ènìyàn tí kò ní ìgbàlà yóò wà nínú adágún iná títí aiyéraiyé, nígbẹ̀yìngbẹ́yìn (Máàkù 9:43-48, Mátíù 13:40-42). Èyí ni ìdí tí ó fi ṣe pàtàkì fún ọ láti gba Ẹ̀bùn Ìgbàlà nísinsìnyí, olùfẹ́. Ọlá lè pẹ́ jù (Jákọ́bù 4:13-15)!

### Báwo ni a ṣe lè gba Jésù Krístì nísinsìnyí?

*Bíbélì sọ wípé: Bí ìwọ bá fi ẹnu rẹ jẹ́wọ́ pé Jésù Krístì ni Olúwa, tí ìwọ sì gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Ọlọ́run jí i dìde kúrò nínú òkú, ìwọ yóò ní ìgbàlà (Romu 10:9).*

1. Gbà pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni ọ́.
2. Ṣe ìpinnu láti yí padà kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ.

gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ wa. Nítõtọ́, àwa kìí ṣe àtìlẹ́yìn fún ẹ̀kọ́ *'Rígbàlà Lẹ́ẹ̀kan, O ti Rígbàlà Tití Aiyé'* tí díẹ̀ nínú àwọn olùkọ́ni Krìstẹ́nì ń polongo fún àwọn ènìyàn. Síbẹ̀síbẹ̀, a yóò yára láti jẹ́ kí o mọ̀ pé Krístì kìí kọ ènìyàn tí ó ti gbà á nítòótọ́ gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà rẹ̀, sílẹ̀ (Jòhánù 6:37-39). Bí ó tilẹ̀ jẹ́ bẹ́ẹ̀, ẹni tí ó ti gba Krístì lè pinnu láti yà kúrò lọ́dọ̀ Rẹ̀, kí ó tẹ̀lé ọ̀nà míràn. Nígbà náà ni a óò wá sọ pé ẹni náà ti kúrò nínú Ìgbàgbọ́ nípa yíyàn tirẹ̀. Àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ mìíràn tún ṣì wà - èyí tí a lè parí èrò sí pé ènìyàn ti yà kúrò lọ́dọ̀ Olúwà. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn á máa jiyàn pé, ẹni tí ó yàn láti kúrò nínú Ìgbàgbọ́ kò fi ìgbà kan ní ìgbàlà ní òtítọ́ tẹ̀lẹ̀ rí. Ṣùgbọ́n kókó-ọ̀rọ̀ wa nísìnyí kìí ṣe nípa *Kíkúrò nínú Ìgbàgbọ́* tàbí *Dídúró sínú Ìgbàgbọ́*. Bá wa ká lọ sí àlàyé kejì!

2. Bí Krístẹ́nì àtúnbí (ẹni tí ó ti ní ìgbàlà) kò bá dáwọ́ ẹ̀ṣẹ̀ dúró, Olúwa yóò tọ sí ọ̀nà tí ó tọ́. Kìí ju ẹnikẹ́ni nínú wa nù. Kàkà bẹ́ẹ̀, yóò bá wa wí lọ́ná tí ó wù ú, bí Bàbá tí ó nífẹ̀ẹ́ àwọn ọmọ rẹ̀ ṣe ń ṣe e (Hébérù 12: 5-11).

Gbogbo èyí túmọ̀ sí pé, ènìyàn tí ó ní ìgbàlà yóò ṣe ohun tí ó bá yẹ ní ṣíṣe lọ́dọ̀ Olúwa tí ó bá dẹ́ṣẹ̀, yóò sì rí ìdáríjì gbà, láìsí ìdálẹ́bi. Gbàrà tí ó bá ti ṣe ohun tí ó bá yẹ ní ṣíṣe, Ọlọ́run yóò gbàgbé ẹ̀ṣẹ̀ náà; á sì dàbí ẹni pé kò sí ohun búburú kan tí ó ṣẹlẹ̀ (Àìsáyà 43:25). Kìí ṣe dandan kí ẹni yìí ṣàlàyé ìgbà, tàbí bí ó ṣe ṣe ohun tí ó yẹ lọ́dọ̀ Olúwa fún ọ, láti dá ara rẹ̀ láre lọ́dọ̀ rẹ. Kí ènìyàn jẹ́wọ́ (fún ọ) nípa ohun tí ó ṣe ní tààràtà tàbí láìṣe tààràtà láti pa ọ́ lára jẹ́ ohun tí ó dára púpọ̀; ó sì lè mú àtúnṣe àjọṣe tí o ní pẹ̀lú ẹni náà, wá. Àmọ́, jíjẹ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ fún ẹ̀dá-ènìyàn kìí ṣe ohun àfilélẹ̀ láti rí ìdáríjì Ọlọ́run gbà. Ohun pàtàkì méjì tí a mú ní dan-dan (bí ẹni yìí bá jẹ́ Kristẹni tí ó ní ìdúró rere) ni, kí ó tọrọ àforíjì rẹ, kí ó sì wá ọ̀nà láti ṣe àtúnṣe níbi tí ó bá ti ṣeé ṣe. Lẹ́yìn tí ẹni náà ti ṣe ohun tí ó yẹ, tí ó sì ń bá ìgbésí aiyé rẹ lọ (nítorí àwọn àǹfààní tí ó ní gẹ́gẹ́ bí ènìyàn tí ó ti ronúpìwàdà tí ó sì ti rí ìdáríjì Ọlọ́run gbà), ìwọ ṣì lè máa ba yodì; kí o máa ronú ohun tí ó ṣe sí ọ ní ọ̀sẹ̀ tó kọjá, oṣù tó kọjá, tàbí àwọn ọdún sẹ́yìn, tí kò dára.

Ó ṣeé ṣe ko máa rò báyìí: *"Eléyìí ò dáa"*; àmọ́ Ìgbàlà nípasẹ̀ Jésù Krístì jẹ́ ohun tí ó jẹ́, pàtó: Ẹ̀bùn Àgbàyanu Oore-ọ̀fẹ́ Ọlọ́run tí Ó fi fún ìwọ náà (1 Jòhánù 2:2). Ìwọ yóò fi ayọ̀ du ara rẹ lórí ilẹ̀-aiyé, àti ìdùnnú àìnípẹ̀kun lẹ́yìn aiyé yìí, tí o bá ń kọ Ẹ̀bùn yìí. Gbogbo wa ni a óò gba ìdájọ́ lẹ́yìn ikú (Hébérù 9:27). Ní ọjọ́ ìdájọ́, ìwọ nìkan ni yóò dúró níwájú Olúwà láti gba ìdájọ́ fún ẹ̀ṣẹ̀ rẹ - kì í ṣe ìwọ àti ẹni tí o dá lẹ́bi fún kíkọ̀ láti gba Ẹ̀bùn Ìgbàlà lákòókò tí o wà láiyé. Olúkúlùkù pẹ̀lú Ìgbàlà tirẹ̀! Yóò ti wá pẹ́ jù láti yí ọkàn rẹ padà. Ó ṣeé ṣe pẹ̀lú, kí o rántí pé o ka ìwé àṣàrò kúkúrú yìí *"tí kò ṣe pàtàkì"* sí ọ lásìkò tí o kàá. Gbogbo ènìyàn tí kò ní ìgbàlà yóò wà nínú adágún iná títí aiyéraiyé, nígbẹ̀yìngbẹ́yìn (Máàkù 9:43-48, Mátíù 13:40-42). Èyí ni ìdí tí ó fi ṣe pàtàkì fún ọ láti gba Ẹ̀bùn Ìgbàlà nísinsìnyí, olùfẹ́. Ọlá lè pẹ́ jù (Jákọ́bù 4:13-15)!

### Báwo ni a ṣe lè gba Jésù Krístì nísinsìnyí?

*Bíbélì sọ wípé: Bí ìwọ bá fi ẹnu rẹ jẹ́wọ́ pé Jésù Krístì ni Olúwa, tí ìwọ sì gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Ọlọ́run jí i dìde kúrò nínú òkú, ìwọ yóò ní ìgbàlà (Romu 10:9).*

1. Gbà pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni ọ́.
2. Ṣe ìpinnu láti yí padà kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ.